# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 705 THURSDAY, MAY 28, 1964 (2D)


## Alakoso Ijọba India Filẹṣaṣọ Bora !

INDIA:— Ggbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo ti awọn enia si bẹrẹsi iṣe idaro nigbati nwọn gbọ iku Ọgbẹni Panditi Nahru, Alakoso Ijọba India ti o ṣe alaisi ni kutukutu Owurọ ana Ọjọ 'ru ti Iṣe Ọjọ kẹtadinlọgbọn Oṣu yi.

Lẹsẹkẹsẹ ti Ọlọla na ku ninu Afin rẹ lẹhin aisan diẹ ti o ti ṣe e fun bi Ọjọ mẹta kan.

Irohin fi ye wa pe ninu ọdun 1880 ni nwọn bi Ọlọla Panditi Nahru o si fi ilẹ bora bi aṣọ nigbati o di ẹni ọdun mẹrinleladọrin (74 years).

Onirohin wa kan ran wa leti pe ninu ọdun 1962 ni Ọlọla Nahru wa se ibẹwo Orilẹ ede Naijiria ti awọn alaṣẹ Ijọba si ṣe e ni ojulowo alejo nigbogbo ibiti o ba lọ nigbana.

A gbọ wipe nwọn ti yan ẹnikan lati ma ṣe adele fun Ọlọla na fun igba diẹ na titi ti nwọn o fi yan ẹlomiran ti yio ma a ba iṣẹ rẹ lọ.

Jakejado gbogbo aiye ni awọn Alakoso Ijọba kọọkan ti nranṣẹ ibanikẹdun ati iroju ranṣẹ si awọn alaṣẹ Ijọba India.

Ki Ọlọrun ki o pa aṣiṣe rẹ rẹ ki o si tẹ ẹ si afẹfẹ rere.

# IYA AJẸ KAN PA ENIA MEJILẸLADỌRUN JẸ!

### O SI SỌ ỌKUNRIN MẸJỌ DI ẸNITI KO LE BA OBINRIN LOPỌ MỌ ! !

MUSHIN:- Ọrọ di boolọ o ya kuro lọna fun mi, nigbati awọn Ijọ Apostolic Mission ni nọmba 6. Iyasuna Stree, Idi-Oro nṣe akanṣe isinọnla kan ti Obinrin kan, Abigael Ayinkẹ, ẹni ọdun mejilelọgorin sare dide larin gbogbo awọn ọmọ Ijọ ti o si nka-ako pe, Ajẹ ni on, enia mejileladọrun (92) ni on tipaje nigbati on ti gba ẹiyẹ ajẹ, on si ti sọ enia mejọ di ẹniti ko le suumọ obinrin mọ lailai ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.



Aworan Oke yi ni ti awọn ero 'ti korayẹ wọ inu Ṣọọṣi ti awọn nwo iya ajẹ na ni ode

Ọmọ on, o si ku awọn meji ninu wọn nisisiyi, ti nwọn nṣe itọju on lọrun ati ni Orun.

### SOBIA

Iya-Ajẹ na tun sọ pe on ni on ṣe iku pa ọkọ on, nigbati ara rẹ ko ya ti aisan keke kan ṣe n ilu Abẹokuta. Iya na ni edeaiyede kan wa larin on ati ọkọ on, ni asiko na gan an ni sobia da on gunlẹ fun bi odindi oṣu meji ti on ko le ṣe nkankan.

Iya na ni bi on ti ṣe wa ninu idubulẹ aisan na, ọkọ on ko tọju on titi ti sobia na fi san.

Nigbati sobia na san tan ni on ba fi ọkọ on dajọ nigbati ajọ kan on.

Iya ajẹ na tun ṣe alaye pe fun gbogbo awọn ero inu Ṣọọṣi pe, on ko fẹ gba ẹiyẹ ajẹ tẹlẹ, ṣugbọn ẹniti o fun on sọ pe, "Akọya ni" ko si ni jẹki iya jẹ on.

O tun ṣe alaye pe aisan kan lo ṣe on ti on fi lọ si Oko-Abẹokuta lati lọ tọju aisan na nigbati on si de oko Abẹokuta iya ti o ntọju on ku aisan na ko si ti san.

Obinrin kan ti nwọn npe ni Iya Kasali lo fun on ni ẹiyẹ Ajẹ, ọmọ rẹ ni o fi ranṣẹ si on pe, ki olọ fi kini na han on. Bi on ti fi oju kan kini na ninu ikoko ni kini na ba wọ inu on lọ, ti on si nriran lọsan ka

WO OJU EWE KẸFA

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ero oja Ogunmokun ati Araromi ba tuka ti nwọn si sare wa wo Iya ajẹ na nibiti o gbe ti nfi ẹnu ara rẹ jẹwọ gbogbo iṣẹ ibi ti on ti ṣe lati igbati o ti gba ẹiyẹ ajẹ na.

Nigbati yio fi to ago go mefa irọlẹ ọjọ na, gbogbo inu Ṣọọṣi na lo kunṣọṣọ ti tomọde tagba nturaka lati le fi oju ara wọn ri iya ajẹ na.

Iya Ajẹ na ko tilẹ ti ju larin ogunlọgọ ọkẹaimoye enia ti o parojọ le iya na lori, ninu Ṣọọṣi ti o si nfi ẹnu ara rẹ jẹwọ fun gbogbo enia pe, Ajẹ ni on ṣugbọn nisisiyi, on ti ṣetan, on si pinnu lati rọmọ Agbelebu Jesu on o si kọ gbogbo iṣẹ okunkun ti on ti nṣe silẹ patapata.

Bi oniwasu ẹni ọwọ J. A. Agbọna ti iṣe olu ṣọaguntan Ijọ na ti ngba dura, laisimi bẹni Iya Ajẹ na tun njẹwọ awọn ẹṣẹ rẹ laitiju larin gbogbo awọn ọmọ Ijọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni ẹni ọwọ J. A. Agbọna ba sare pe oniwe irohin wa Ejongboro ninu ẹrọgbohuugbohun, pe ki o fi ohunkohun ti oba nse silẹ, ki o si tete ma sare bọ.

Logan ni oniwe irohin ti yara gbe moto ti o si sare lọ si Ṣọọṣi na.

Awọn ero ti nwọn wa ninu Ṣọọṣi na le ni ẹgbẹdọgbọn (5,000) enia. Bi o tilẹ jẹ wipe aye na lati wọle; ṣugbọn oniwe irohin wa rapala wọle.

Iya na ṣe alaye pe, o ti le ni Ọdun mẹjọ ti on ti gba ẹiyẹ ajẹ na, Lati igbati on si ti gba ẹiyẹ ajẹ na. on ti pa enia mejileladọrun, enia mẹjọ ni on si pa ni Ọkọ tan patapata ti lo si fi di bi on ti nsọ lẹnu yi, awọn Ọmọkunrin mẹjẹjọ ko le ba Obinrin lopọ mọ.

Iya na tun ṣe alaye pe, Ọmọ mẹta pere ni on bi ni aiye on, ṣugbọn nigbati asiko to ni on ba fi Ọkan ninu awọn Ọmọ na dajọ.

Nigbati ekeji ṣe nkan ti o dun on ni on ba sọ Okuta nla (Ọlọ) kan mọ lọrun, aisan nla kan ṣe. ṣugbọn awọn kan tun Okuta na lọrun rẹ, ko si ku mọ.

Iya na ni Ọmọ kanṣoṣo ni on pa ninu



Aworan oke yi ni ti Rev. J. A. Agbọna ati Abigael Ayinkẹ ninu Ṣọọṣi

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 10 )

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Gẹgẹ bi ẹnyin papa ti mọ pe orun ko mọ iku, ogboju-le-ogun ti sun lọ fọn-fọn, iyawo re wa ninu ibanujẹ, o nyan ho o, osi nrọ paabi bi ejo agbanu inu rẹ ko dun, toripe bi lọ ti ọkọ rẹ nlọ, le jẹ arimọ fun awọn mejeji

O ji ọkọ rẹ, o bẹrẹ si sunkuu, Ogboju-le-ogun tikalara rẹ bẹrẹ si su kun pẹlu n tori pe o fẹran iyawo rẹ pupọ ko si fẹ fi silẹ. Bi ko ba di karaugida tan, ṣaṣa ni ọkunrin ti o nf fi iya o rẹ silẹ Gẹgẹbi ẹnyin papa ti, mọ ọrọ ọkọ l'aiya, Eidẹra' ni ọrun wa de ba wọn lojiji lori ibusun wọn ọmuti gbagbe iṣẹ, nwọn tun nbaṭere aniyan boṭiti ilẹ fi fẹrẹ mọ.



AWORAN OKE YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Ẹnyin papa mo pe, aiye oko ajerọrun ni, toripe orun kanṣoṣo ti o ku fun Ogbojuleogun ati iyawo rẹ lati jijọ sun pọ niyẹn. Ademuyiwa npalẹ ogun mọ ni ọrọ alẹ ọjọ na, orisa oke majẹki o tẹnu mi bọ.

Iyoku dọwọ yin o, ẹnyin oluka itan mi bi a ba ni ki ẹmọran mọ, nṣe ni mọ o toto o ṣebi owe o. Ni fẹẹrẹfẹ, Ogbojuleogun dagbere fun iyawo rẹ o ni, Iyawo mi ọwọn, olufẹ mi ọwọn, nko fẹ ki o ba inu jẹ, adura ni mo fẹ ki ọ fi sinu pe ki ngma ko esu, ki ngma ko agbako, ki alọ mi dara ki abọ mi sunwọn, n toripe ti mo ba fi le pada ni alafia, yio dara fun emi ati iwọ; gbogbo wa yio dẹni ọla, ao i dẹni iyi, okiki wa yio si kan ku ni aiye ka.

Nigb ti ọmọ wa Ẹgbẹji, majẹki ebi pa a, masi se jẹki orugbọ gbẹ ẹ

Tọju ara rẹ pẹlu, maṣe rin ode oru nitori awọn alujannu buburu. Bi Olawa ko ba kọ iṣẹ ẹru rẹ, ao pade ni alafia o Onii tun bẹrẹ si bọ peroporo lọju iyawo rẹ gẹgẹbi ẹnyin papa ti mọ iru ifẹ ti obi ni si ọmọ nigbati, ọmọ Ogbojuleogun bẹrẹsi sọkun pe on yio ba baba on lọ, o bẹrẹ si tan an jẹ ṣugbọn ko gba.

Ṣugbọn nigbati Avọrunbọ yọ si wọn lojiji ti o ṣi kigbe pe ha! kini ẹ tun nduro wo, asiko nlọ o, ni Ogboju-logun ba gbọwọ le ọmọ rẹ Ẹgbẹji lori, o si bẹrẹsi ki i mẹsan-mẹwa bayi pe: Ẹgbẹji Ologun ọjọ kan, ogunkan. adayi ti ko jẹ nu, maṣe ṣe aisan, dakun ma yọ iya rẹ lẹnu ti mo ba lọ o pulẹ ayọ ni ao fi ri ara wa o gẹgẹ bi ẹnyin paapa ti mọ pe ko si ọmọ karọ o jire ti a le ki, ti inu rẹ ko ni dun, o bẹrẹ si rẹrin bẹni baba fi tan an, osi yọọ silẹ lọ. Bi oti nlọ ni iyawo rẹ nsin in lọ, nigbati nwọn ku si ẹnu bode, nwọn duro nibẹ ni iyawo rẹ ti dagbere fun.

Mo fẹ ki ẹ mọ daju pe, ọjọ ti eṣu ọdara lulu okiri ọkọ ti ba wọn ṣegun, ni o ti nṣe ọmolẹhin ogbojule ogun ati awọn ẹgbọn rẹ ni kukuru nwọn jọ nlọ si ilu Ajirann.

Iyawo rẹ bẹrẹ si dagbere fun wọn, o pe Eṣu ọdara, ogboju le ogun ati ẹgbọn rẹ nwọn joko lori apata, nwọn bẹrẹ si se isi igbe-hin toripe ko si ohun t Iyawo ogboju le ogun le se ti ko ni ni ọvọ ti sọvọ ninu,

Ohun ti a nwa lọsi Ṣokoto a ri ni okun Ṣokoto ni ti ọrọ Ige ati ti Iyawo aburo rẹ wọn tẹnu bọ, orin se ẹnyin paapa mo pe nibiti awon ba ti nyin Ọlọrun, Eṣu ki sun mobe logan ni nwon fẹ esu ku, o si si lo. Orin ti nwọn nkọ lọ jọ na ni pe:— ka pade, ka pade. ni woyi amọdun, k' Ọlọrun ṣo wa ka tun pade.

Bi nwọn ti ṣe "Amin tan ogboju-le Ogun f'ẹnu ko aya rẹ lẹnu, iyawo pada sile, ọkọ ati awọn ẹgbẹ rẹ mu irin ajo pọn.

Nwọn rin fun ọjọ marun gbako, ninu papa, nwọn ko ba ohun alaye kan pade, afi kukute ti nwọn nri lọtun ati losi, nwọn ko gbohun ẹiyẹ pẹlu, ilẹ ati ọrun jọ pade lọtun ati losi, awọ sanmọ dudu rẹgẹdẹ bi ẹnipe ojo fẹ rọ, ṣugbọn ẹyọ ojo kan ko kan rara."



Ogbẹni J. O. Shoyinka

Nigbati o di owurọ ọjọ keji ni nkan bi agogo kan ọsan, nwọn ri atioro kan lọkọkan tin-in, ero wọn ni pe ko ju abọ busọ lọ mọ. Ki nwọn de bẹ. Orun ngmura ati wọ ni nwọn de ahere yi-ahere na ko ga ju ile ti awọn "Arara Eskimo' ngbe lọ, ẹnu ọna rẹ ko ju oju korofo isana lọ-awọ ara enia ni awọn fi bo o yika. lọrọ kan, abami ile ni iṣe.

Awọn ẹgbọn rẹ nbi ara wọn lere pe tani yio kọkọ kan ilẹkun yi? Nwọn joko fun nkan bi wakati kan, ko si ẹniti o laiya lati kan an. Gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ pe Ogboju-le-ogun laya pupọ, eyiti iba fi kan ilẹkun yi jẹjẹ, nṣe lo ko ẹṣẹ bo o.

Eyi mu ki "AGIDI' baba bilisi binu, nitori on ni enia iṣẹ bale ile na. A gbọ binu itan pe aja ilẹ lo ngbe, atipe o binu wọ ile lọ ni.

Agidi fi ibinu bu ramu ramu bi kiniun ninu aja ile pe tali olori buruku ti o nkan ilẹkun ni iba gbe ọmọ enia ko tẹ mi lọrun. Ni mo se fi ile mi si aja lẹ. Mo si kọ ile sugudu si ori rẹ lati ma siji bo mi

Ọba lẹ tete yara fẹsẹ fẹ ki nto jade iba dun pupọ a ki ri ajẹ ku oro ni ogo fi ọ se Ogbojuleogun daa lohun pe emi enia abiruo lori lo nbaa sọrọ bẹẹ Abi oko mọ mi o ko gbọ ohun mi ni e mi ni Ogboju le ogun sọ ọmọ Ajẹ nko' Agidi temi ju tirẹ lọ

Mo ṣe ako pọ ọrọni tun ọdun jojọ. Mo si ti ba awọn Ọgbẹni iwin bi Iroko Araba, Kukute Iwin odo lo po amb sibọsi iwọ Aditi lasan lasan yi.

Jade sita ẹpa yio at loni inu bi Agidi t bẹ gẹẹ, o pe lẹ loruko to nje, ile lanu lo ba bẹ ade nko le si se ala ye iru eniti Agidi je o ga to ẹsẹ mẹfa pa rẹ kọkan to itan ọmọde ọrun rẹ ki to ẹsẹ Ajanaku isan ara rẹ ri wara-wara o dabi gbongbo igi ni kukuru Ogbojuleogun ko de ejika rẹ

Agidi rerin muse ko tilẹ fẹ ba Ogbojuleogun ja to ri pe o kere sii eni iwọ ọmọ

WO OJU EWE KARUN

# IWE SI OLOTU

## Ọgbẹni Shoyinka, Ẹ ku Iṣẹ

O jẹ didun inu mi lati kan sara si ọgbẹni wa J. O Shoyinka ẹniti o nkọ itan Ajiran Ilu Awọn Oku pe o ku iṣẹ, mo gba loga fun ṣugbọn ati oye ti o nlo lati kọ awọn itan na jọ, o ṣe iṣẹ nla, gbogbo awọn ti o mọ itan arosọ ni ede Yoruba ni o gba pe ọgbẹni Shoyinka nṣe iṣẹ gan an ni,

Mo gbadun itan na ni ti emi lati igbati itan na ti bẹrẹ ni mo ra iwe itan na jọ fun alafia ati gbadun ẹmi mi, paapa fun awọn ọmọ mi pẹlu.

Yoruba ni o npa lowe wipe, ohun ti aba fi oni ṣe ọrọ itan ni



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

yio da bo dọla, itan yi jẹ itan ti nwọn ọmọ wa le mọ ka lẹhin ọla.

Akatunka ni mo nfi itan na ṣe, bi mo ba bẹrẹ lati ibẹrẹ itan na, o si di igbati mo ba ka itan na tan tabi de ibiti o kọde ki nto simi.

Nitorina mo ki ọgbẹni wa J. O. Shoyinka ku iṣẹ ori, iṣẹ na ga loju mi ki ọpọlọpọ enia ko pe to ba yẹn, Ọlọrun ko ni gba ọpọlọ ti o nlo lọwọ rẹ amin.

Olotu ẹku iṣẹ Ọlọrun ko ni doju ti nyin o aṣẹ.

Emi ni,
Jacob,
ONDO.

## Ilu Ọra NFẹ Ọlọpa

Olotu

Inu mi yio dun pupọ ti ẹba le gba mi aye ninu iwe yin oloyin mọmọ yin ti njade ni ojojumọ lati kesi Ipinlẹ Iwọ Orun Nwijiria lati fun ilu Ọra-Igbomina ni Ọlọpa.

Otọ, o si yẹ, bi ilu na ti tobi to ti osi ni okiki to ojẹ ohun abuku pe ko si Ọlọpa nibẹ rara.

Nitori na mo bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati fi eleyi ṣe eto.

Emi ni
Daniel Adeniyi
Ile - Ate

## A Nfẹ Itan Ilu Awẹ

Olotu, Jọwọ gba mi laye lati kesi awọn opitan ati awọn agbagbe ilu Awẹ pe anfẹ mọ itan ilu Awẹ nitori ẹnyin, na ai o pa lowe ni owe pe bi ọmọde ko ba gbọ itan a gbọ arọba, toto, o jẹ bi owe ki ole jẹ arikọgbọn fun awọn Ọdọ ilu Awẹ. Ki asi inn le mọ bi ilu wa tiṣe ṣe.

Mo ri peawọn Opitan ati agba gba ilu awẹ yio ba ṣe eto nipa rẹ ki Olotu si ba wa tete tẹ jade ri oba ti tẹ lọwọ

Olotu, mo dupẹ Oluwa yio ma ṣe amọna yin O

Emi ni
Adeniyi Akintokun
AWẸ

## Mo Ba Erukobodo Yọ

Mba sọpẹ bi Olotu gbajumọ Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe Irohin rẹ lati ki *Baba* wa Ẹrukobodo ku ewu ti ọmọ titun jojolo ti Ọlọrun fi ta ni ọrẹ.

Mo ki baba wa yi pe o ku ewu o, Oluwa ko wo ọmọ na ki Ọlọrun da ọmọ na si aiko tete gbọ nipa ọmọ na ni ngko ba wa ni ọjọ ikomọ lati wa fi ete ko irẹsi ki si mu emu ogucọ si Baba wa na lọrun, nitori ẹni nla ni Ẹrukobodo nṣe a si ma ngbadun rẹ ninu iwe yi,

Ki nto pari ọrọ na mo fẹ bere lọwọ baba wa na pe kini ṣe ti a ko fi ri owọ rẹ mọ ninu iwe Irohin Imọle,? Jọwọ Ẹrukobodo a nfẹ ọwọ rẹ o, orungbe rẹ ngbe awa onkawe Irohin Imọlẹ, tabi Olotu ṣẹ ọ wi ki ngbọ?

Emi ni
Olofofo
EKO



Ọgbẹni Ẹrukobodo

## Yoruba Debate

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ẹgbẹ Ariyanjiyan (Debate Club) ti Ẹgb Imọlẹ Aiye yio ṣe ariyanjiyan lori Iṣẹ ọwọ ha pe ju Iṣẹ Iwe Kika lọ bi ? ni ọjọ Sunday ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu yi ni deede agogo meji ọsan (31/5/64).

Nitorina a pe gbogbo enia lati wa wo ere na. A tete de ṣe pataki.

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati lo ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Erok wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ wọ Bọọsi ti o nlọsi Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O A FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Ẹgbogi Awo Igba Arun | |
| Iwe Ẹgbogi Ajẹbidan | 20/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 25/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 5/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Ṣiṣẹ | 20/- |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6d |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO *PỌKU* NI A *SI* *NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*

# Baba Kan Ati Awọn Ọmọ Rẹ Marun

Ni igba kan, Baba kan wa ti o ni awọn ọmọkunrin marun, ṣugbọn Baba na ti ndarugbo lọ. Nigbati o di ọjọ kan ni o ba pe awọn ọmọ rẹ yi gẹgẹbi o tiṣe mọ pe wọn telẹtẹlẹ, ti o si ma nsọrọ fun w ọ n lorişirişi, lori ifọwọsowọpọ.

Nigbati Baba yi nmura ati fi aiye silẹ, o tun pe awọn ọmọ rẹ mararun jọ gẹgẹbi o tişe ma nse tẹlẹ. O si sọ fun nwọn pe ki onikaluku nwọn lọ si inu igbẹ, ki nwọn si bẹ igi marun-marun ti ọkọkan si gun gẹgẹbi nwọn tise ga mọ. Onikaluku awọn ọmọ na si ṣe bẹ. Nigbati nwọn ko awọn igi na de ọdọ Baba wọn Baba na tun nsọ fun wọn pe lori ohun ti on ma nbawọn sọrọ lorirẹ lojojumọ ni on tun fẹ se alaye rẹ fun wọn yi. Baba na si paṣẹ fun awọn ọmọ rẹ na wipe, ki nwọn di igi na p ọ pẹlu Okun, nwọn si ṣe bẹ. Nigbati nwọn di tan, o sọ fun awọn ọmọ na pe ki awọn mararun dimọ igi n a ki nwọn si da si wẹwẹ.

Awọn ọmọ na sa gbogbo apa wọn, ṣugbọn nwọn ko le da igi na si wẹwẹ. Baba na si tun paṣẹ fun wọn pe ki nwọn tu igi na. Nigbati nwọn tu tan, o si fun ọkan ninu awọn ọmọ rẹ na ni igi kan wipe ki o gbiyanju lati da igi na si wẹwẹ. Ninu igbiyanju ọmọ na, o si yege Baba awọn ọmọ marun na, nsọ fun wọn pe, eyi ni alaye ohun ti on nsọ fun wọn lojojumọ wipe, bi awọn ba fi imọ sọkan, ti nwọn ba ni irẹpọ, ti nwọn si tun fọwọsowọpọ larin ara wọn, ọta kankan ko le wọ arin wọn, Ki o si bi wọn ṣubu. O si tun pe akiyesi wọn si igi ẹyọ kan pe, bi nwọn ba ya ara wọn lọkọkan, were ni ọta yio kọlu wọn ti yio si bi wọn subu gẹgẹbi nwọn ti se da igi yẹn.

Bẹni Baba yi ku bi o ti pari ọrọ rẹ yi tan, ti awọn ọmọ na si ma riri ifọwọsowọpo.

# ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ire ni ọjọ oni yi yio jẹ fun ọ fun imọran titun ti o ṣẹṣẹ gbe kalẹ. Kere ni oni jẹ bi ọrẹ ba wa ki ọ, tabi bi alejo kan ba wa ki ọ Gbogbo enia yio ma gbadura rẹ.

PISCES Feb 19 - Mar 20) Ọro rẹ kan yio da ija silẹ ṣugbọn jwọ ko gbọdọ binu, nṣe ni ki o ṣe suru, ki o si bọwọ fun awọn agba iṣẹ rẹ yio ma lọ daradara, bi o ba di ọsan, ki o rin faaji lọ.

ARIES (Mar 21 April 19) Ori rẹ ati ọgbọn rẹ. pe, ṣugbọn ki o ṣe pelẹpẹlẹ nigbati o ba fẹ lo ọgbọn na nse ni ki o kọkọ danwo maṣe binu abisodi.

TAURUS (April 20 - May 20) Iṣẹ ati owo yio jẹ şişe ati lilo fun ọ. Iwọ yio tu aşiri obirin kan wo, tọju nkan ti ara rẹ

GEMINI (April 21 - June 21) Awọn ẹmi ọrun tako ọ lọnakọna, ijo ati ere şişe rẹ yomu itẹlọrun wa.

CANCER (June 22 - July 22) Ọjọ i r e lọjọ oni, ọpọlọpọ ọrọ li ati yanju ṣugbọn maṣe huwa buruku, nṣe ni ki o ni ọrẹ titun

LEO (July 23 - Aug 22) O ni lati ṣe o r i r e loni. lọnakọna ọwọ rẹ yio tẹ owo tabua ṣọ awọn oja ti o ni lati ra loni ohun ti o tọ ni ni ki o si ra

VIRGO (Aug 22 - Sept 22) Awọn iṣoro kekeke ti o mbẹ loju ọna rẹ ni iwọ yio ṣẹgun rẹ. Ṣugbọn maṣe jẹki nkan miran tun fa ọkan rẹ sẹhin, lọ ki o lọ ki awọn ọrẹ rẹ loni ninu ile wọn.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Bi o ba fẹ sọrọ owo, o ni lati lo ọgbọn ori ki o maṣe ṣe keta, maṣe sọrọ ti yio mu ipade binu ki o si ṣe jẹjẹ niti iṣẹ rẹ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Lo egbogi awure rẹ iwọ yio si ṣorire jaburata. Iṣẹ yio ma lọ siwaju adehun yio si wọ ara wọn.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Kuku ṣe gẹgẹbi o ti nṣe latijọ nigbati o mbẹ lẹnu iṣẹ ki o ba lebọ lọwọ ijọngbọn alejo kan ati kuro lọwọ obinrin gbajumọ kan,

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Bi o ba jẹ pe oju rẹ ko le kuro ninu ohun gbogbo, owo yio ṣọwọn fun ọ fun igba diẹ. Maṣe tete ma bẹ lu ọrọ ki ọrọ ara rẹ ba le ma lọ geregere.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




OLUBORI EGBOGI "IKỌ

# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọbi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni P O R A L ojulowo hanunhahun, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaaya, Ikọ lile, Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone:- 2278 (Ọj, Lagos Nigeria
8, Palmchurch Street, Ita Faji)

ADEDUN CHtEMIST
14' Wakeman Sreet, Yaba

# Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Ayie ni ọjọ keje oşu kẹfa (7/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

# ỌTẸLẸMUYẸ NKI NYIN O

ỌTẸLẸMUYẸ nki yin o, mo ki ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ lai da ẹnikan si, bakanna ni mo tun si fila fun Olotu Irohin Imọlẹ. Gbogbo yin ko ni ṣẹ ẹ ti lagbara Odua

Emi Ọtẹlẹmuye funrara mi, ọkunrin ti a fi nsepe sọ ọkunrin ti di Sango nisisiyi, apo awọn ọwọ jaguda Mushin ni mo ha si nisisiyi ọrọ ani wa di agbagbara to ri bọlẹ, o wa ku atiyọ.

Mo ti sọ pe, nko ni salai sọ lu awọn ọmọ jagudi Mushin nitoripe, nse ni wọn nsọsin-sọra ni Mushin bi nwọn ti fẹ, gbogbo awọn obinrin ọja ni nwọn si nbẹru wọn bi Ọlọrun ẹ'ẹda wọn.

Ohun ti m fi vi bẹ ẹ ni pe, ti nwọn ba wọ ọja Mushin, nṣe ni awọn obinrin ọja m . a nda nkan ribiribi jọ fun wọn, ki nwọn ma ba ko wọn ni ọja Eyi ha ṣe gbọ si eti ni ilu ijọba?

Tori idi eyi, ajadiju ni ngo ba awọn ọmọ jaguda na ja, ki nwọn ba le jẹki awọn r'oju s'oju.

Laipẹ yi mo nsọmọ lọ si ọja Mushin lati lọ ṣọ awọn ọmọ jaguda na wo bi otitọ ni awọn enia nsọ tabi irọ. Mo wa gba lotitọ pe ododo ni.

Bi mo ti joko ni buka ẹrẹ mi kan ni isọ alata ni mo ri ọkunrin firagba kan ti o nda ọja ru bọ bi eegun ni waranṣeṣa o ti talu obinrin kan, iṣẹju aya, awọn ti o surubo obinrin ti mo nwi na le ni mefa.

Nigbati obinrin na ri i pe ọmọ jaguda ni wọn nṣe ni o fi igbe Ole! Ole! ta ṣugbọn ki o to yira pada nwọn ti fẹ ata gigun si loju lero pe, nwọn yio ri owo ja ọ ni idi, bi Ọlọrun fẹ, nwọn kori epinni lọwọ rẹ. Ni nwọn ba tuka m o lori.

Ohun ti o yami lẹnujulọ ni pe, bi awọn ọmọ jaguda ti ṣe obinrin na ṣikaṣika to, ko si ẹniti o gbeja rẹ.

Nigbati ritiriti na rolẹ tan, ni mo wa bere lọwọ obinrin alata kan pe, kini ṣe ti ẹ ko ṣurubo awọn ọmọjaguda yẹn ki ẹ si fa le ọlọpa lọwọ.

IDAHUN

"Nwọn ni toto fun un ẹniti o ba dasi ọrọ wọn tabi o sọ pe on ri wọn, nṣe ni wọn yio ko ni eru tan patapata nṣe ni a mbo wọn, bi ẹni bo orisa, iba ṣepe obinrin yẹnti tetemọ wọn, ki o si fi ọi sile marun bo wọn ninu ni, ẹwọn ki ba ti ṣe "ṣege" bẹ fun

Ọrọ re o! Ọrọ re o!! rẹpete emi nikan ko ni fi ọrọ ti mo ri yi sinu ara mi ki o ma ba a wu mi nikun tori idi eyi mo bẹ ẹyin Ọlọpa Mushin si ki ẹ ba wa mojuto ọrọ awọn omọjaguda ki awọn ti nwọn nta, ti nwọn si nra ba le ni ifọkanbalẹ lati ma a ṣọwọ wọn Ọba ni ogba alailara e dakun ẹ gbawa o, Ọtẹlẹmuyẹ nrele o, ao ma gburo ara wa si rere. Ki Oluwa ko ba se ko iṣẹ ẹru rẹ, awọn agbero Mushin ni ngo tun solu— No Finish' ni ngo si fi wọn ṣe lọd awọn Ọlọpa amumọto.

## Ilu Oke-Amu Ni Ilọsiwaju Ninu Ọdun Yi

(lati Ọwọ Saka Oladeji)

Gẹgẹbi awọn ilu nilẹ Naijiria ti ndagba ti nwọn si ntẹ siwaju ninu awọn mereme-re ti ilu ni lati ni ati awọn enia pataki ni arin ilu, Nitori o ku awọn miran ti ti a rfẹ sibẹsibẹ a si tun ndupẹ lọwọ Ọlọrun fun ibiti o tun ilu wa lọwọ de ilu Oke-Amu ko si lẹhin ninu awọn ilu to wa ni agbegbe Igbomina Opẹ ni fun Ọlọrun.

Gbegede gbina ni ọjọ ti Alhaji Raji Adegbọla ti ilu mimọ Mẹkka de ni ọjọ Abamẹta ti ṣe ọjọ kẹsan oṣu yi, Bi o ti nsọkale ninu ọkọ ni awọn enia ti wa ki ku abọ, ti enia po bi eṣu elomiran lero pe ọba kan ni ode, eyẹ ọjọ na pọ gan ni.

Ni awọn mọto ulafla ati ayọkele ba de awọn ọmọ ilu Oke-Amu to wa pade Alhaji Raji Adegbọla ba rọ sinu awọn mọto na, ni ago go mọkanla alẹ ni nwọn gbera ti nwọn si de Oke Amu ni agogo mẹrin arọ ọjọ keji.

Bi nwọn ti wọlu ni ariwo tun ta gẹe, ti gbogbo ara ilu njo, ti nwọn si nyọ Inu awọn ọmọ Oke Amu dun wipe awọn ni Alhaji kan ninu ilu awọn. Nwọn jo titi nigbati ijo na kara tan ni nwọn ba jo lẹ si ilu Ipapọ, Iṣẹyin, Okaka, Baba Ọdẹ ati Igbo aiye ati bẹ bẹ lọ.

Diẹ ninu awọn to ba Alhaji lọ si Oke-Amu ni yi Saka Oladeji, Lamidi Ajibade, Jimọh Bello, Yaya Ipade, Sadiku Oladoṣu, Salawu Lawani, Busari Adegbenro, Lasisi Aderohunmu Jimọh Salawu Raji, Tiamiyu ati Alhaji Raji Adegbọla.

Ẹ ku iṣẹ o. Ọlọrun yio bo aṣiri yin o.

LATI OJU EWE KEJI

Lekere yi ika kan ni ngo fi se o lorun iwo awọnibaku ọmọ kekere yi wa ko oni tire niwaju.


AFRICAN SPECIAL

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.

